# ISỌDIMIMỌ́ ISAIAH

**Isaiah 6:1-13**

**ẸKỌ 350 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Ẹnyin ọkọ, ẹ fẹran awọn aya nyin, gẹgẹbi Kristi si ti fẹran ijọ, ti o si fi ara rẹ̀ fun u; Ki On ki o le sọ ọ di mimọ́ lẹhin ti a ti fi ọ̀rọ wẹ ẹ mọ́ ninu agbada omi. Ki On ki o le mu u wá sọdọ ara rẹ̀ bi ijọ ti o li ogo li aini abawọn, tabi alẽbu kan, tabi irú nkan bawọnni; ṣugbọn ki o le jẹ mimọ́ ati alaini àbuku" (Efesu 5:25-27).**

**I Iran Ọlọrun Mẹtalọkan ti a fi han Isaiah**

1 Isaiah ri iran naa lẹyin ti a ti pe e si iṣẹ wolii, o jẹ ẹni iwa-bi-Ọlọrun nitori a ti da a lare, Isaiah 6:1; 1:1

2 Iran naa jẹ ti Ẹni Mẹtalọkan mimọ́, alagbara ailopin, Isaiah 6:1-3, 8; Johannu 12:41; Iṣe Awọn Apọsteli 28:25; Ifihan 4:1-11; 5:6; Esekiẹli 1:1-28; Orin Dafidi 72:19

3 Awọn ohun ti o ri ninu iran naa jẹ awọn ohun ijinlẹ, Isaiah 6:4; Ẹksodu 40:34, 35; 1 Awọn Ọba 8:10, 11

**II Isaiah Ri Aipe Ara rẹ, lẹyin eyi Isọdimimọ́ Rẹ Tẹle e**

1 Iran ẹwa iwa-mimọ́ Ọlọrun yii mu ki Isaiah ri idibajẹ ẹda ainilaari ti rẹ̀, Isaiah 6:5; Ẹksodu 33:20; Luku 5:8; Matteu 5:8; Heberu 12:14

2 A sọ Isaiah di mimọ́ nigba ti ẹ̀ṣẹ́ ina kan ète rẹ̀, Isaiah 6:5-7; Orin Dafidi 51:2, 7; Esekiẹli 36:26

**III Ipe Isaiah ati Aṣẹ ti a fi rán an jade**

1 Lẹyin isọdimimọ́ Isaiah, a pe e si iṣẹ kan ti o jẹ pataki ti o si nipọn, Isaiah 6:8; Gẹnẹsisi 17:1-22

2 Ifi ara-rubọ atọkanwa rẹ̀ ṣí ọ̀na silẹ fun Ọlọrun lati fi iṣẹ kan pato, le e lọwọ, Isaiah 6:8-13; Ẹksodu 3:1-10; 1 Awọn Ọba 19:19-21; fi we 2 Awọn Ọba 3:11, 12; Iṣe Awọn Apọsteli 13:2

## ALAYE

### Iran ati Ẹkọ ti o Kọ́ Ni

Awọn ẹkọ ti a ri kọ́ ninu iran Isaiah pọ pupọ, ninu wọn ni iṣipaya ti Mẹtalọkan Mimọ́ ju lọ. Pe Ọlọrun jẹ Mẹtalọkan hàn gbangba nitori pe Isaiah ri Oluwa o si gbọ́ bi awọn ẹda Ọrun ti n fi iyin ilọpo mẹta fun Un. Iru iyin ilọpo mẹta yii ni awọn ẹni irapada ti o wa niwaju Itẹ Ọlọrun yoo maa fi yin In nigba ti Ipọnju Nla ba wà lori ilẹ ayé (Ifihan 4:8; 5:8-10). Ki i ṣe eeṣi ni o mu ki iyin wọn pin si ipa mẹta, apa kọọkan ninu iyin wọn wà fun Ẹni kọọkan ninu Mẹtalọkan, nitori kò si aṣiṣe lọdọ Ọlọrun. Awọn itọka miiran tun wà ninu iran Isaiah ti o fi han pe Mẹtalọkan ni Ọlọrun.

Ọlọrun Baba wà nibẹ, nitori Oun ni a n fi hàn bi Ẹni ti o joko lori Itẹ ni Ọrun. Nisisiyii Kristi joko lọwọ ọtun Itẹ nì, Ẹmi Mimọ́ Olubukun si wà ninu ayé O n fi òyé yé "araiye niti ẹ̀ṣẹ, ati niti ododo, ati niti idajọ" (Johannu 16:8). Ṣugbọn Johannu Ayanfẹ wi pe nigba ti Isaiah ri Oluwa, o ri Jesu! (Wo Johannu 12:37-41). Ati ninu Iṣe Awọn Apọsteli a kà wi pe Ẹmi Mimọ sọrọ nigba naa! (Wo Iṣe Awọn Apọsteli 28:25-27). A fi iyin ilọpo mẹta naa fun Ọlọrun Mẹtalọkan -- Ọlọrun Baba, Jesu Kristi Ọlọrun Ọmọ ati Ẹmi Mimọ.

Ni afikun awọn ijẹri wọnyii, a ri i pe nigba ti Isaiah gbọ́ ohùn Oluwa, oun kò gbọ́ ohun ẹnikan ṣoṣo bi kò ṣe ohùn ti o ju ti ẹnikan ṣoṣo lọ, ti o si duro gẹgẹ bi ohùn kan, nitori Oluwa wi pe: "Tali **Emi** o rán, ati ta ni o si lọ fun **wa**?" A fi iṣẹ rán Isaiah gẹgẹ bi iranṣẹ Mẹtalọkan, ṣugbọn iṣẹ ti a fi rán an ti ọdọ Ọlọrun ti O parapọ̀ ṣọkan wá -- iṣọkan ti kò lè yé ẹda (Wo Johannu 17:21-23; Heberu 2:11).

Ori iwe yii n kọ́ wa pẹlu pe Mẹtalọkan ti wà lati ayebaye ati titi ayeraye. "Mimọ́, Mimọ́, Mimọ́, **li** OLUWA awọn ọmọ-ogun" li orin-iyin ti n tọka si i pe Kristi wà ninu iwa-Ọlọrun nigba naa. Gbogbo awọn wọnni ti n wi pe nigba ti a bi Kristi ni Bẹtlẹhẹmu ni O ṣẹṣẹ bẹrẹ igbesi-ayé Rẹ̀ n ṣe aṣiṣe nla. Ẹni ti

“a ti pa lati ipilẹṣẹ aiye” fun awọn ẹda ti n ṣegbe (Ifihan 13:8), “O mbẹ lãye titi lai lati mã bẹbẹ fun wọn” (Heberu 7:25).

A kọ́ wa pẹlu pe iyin ati ọlanla yẹ fun Ọlọrun wa, a si gbọdọ fi tọkàntọkàn fi wọn fun Un. Awọn iranṣẹ ti o ga ju lọ nibi Itẹ bo oju ati ẹsẹ wọn ni ipo ibuyin fun, wọn si n fi gbogbo agbára wọn yin Ọlọrun logo. Bi awọn ẹda alai lẹṣẹ ti n duro niwaju Olodumare ba le ṣe eleyi, meloomeloo ni awa ti a ti rà pada nipa Ẹjẹ iyebiye nì ni lati ṣe bẹẹ pẹlu. A ni lati fi gbogbo iyin wa, ijọsin wa, ifọkànsin wa, iṣẹ-isin wa – ani gbogbo igbesi-ayé wa -- fun Un pẹlu irẹlẹ ti o jinlẹ jù lọ. Awọn ẹda mimọ́ wọnyii n yin In nigba gbogbo -- awọn ti kò mọ ẹ̀ṣẹ ri, ti wọn kò si mọ titobi oore-ọfẹ irapada ati ifẹ Ọlọrun si wọn ri. Iyin wa gbọdọ ju ti wọn lọ, nitori ti awa ti mọ ifẹ ati oore-ọfẹ Rẹ̀, ati aanu Rẹ̀ ti O n na ọwọ́ Rẹ̀ si wa lọjọọjọ ni igbesi-ayé wa.

**Isọdimimọ́ Isaiah**

Isaiah jẹ́ eniyan Ọlọrun nigba ti a fi iran yii hàn án. Wolii Ọlọrun ni oun i ṣe nigba naa. Gbogbo awọn wolii Ọlọrun jẹ́ eniyan mimọ́, bi o tilẹ jẹ pe Isaiah kò i ti ri isọdimimọ́ patapata gbà ṣiwaju akoko yii, sibẹ a ka a si ẹni mimọ́ gẹgẹ bi o ti n ṣẹlẹ ni igbesi-ayé awọn ti a ti dalare nitootọ. Ṣugbọn akoko kan de ninu iriri Isaiah bi o ti má n ṣẹlẹ ni iriri igbesi-ayé olukuluku Onigbagbọ́ ti a ti dalare bi o ti n rin ninu imọlẹ, nigba ti o ba ri isọdimimọ́ gbà, ninu iriri ẹsẹkẹsẹ ti o daju ninu iṣẹ isọdimimọ́ patapata ti a ṣe ninu ọkàn rẹ̀. Iwamimọ́ ti a kà si ni lọrun nipa oore-ọfẹ Ọlọrun jẹ ti oluwarẹ niwọn igba ti oun ko i ti ri imọlẹ nla tabi anfaani lati wá oore-ọfẹ iwamimọ́ nì ti a n fi fun ni nipa agbára ẹbun oore-ọfẹ Ọlọrun – Jesu Kristi, ati Ẹjẹ Rẹ̀ ti a ta silẹ -- ni akoko isọdimimọ́ patapata.

Nigba ti Isaiah ri i bi ipo rẹ̀ ti ri niwaju Ọlọrun, ti mimọ́ Ọlọrun si fara hàn niwaju rẹ̀, o kigbe ni ibanujẹ ọkàn pe: “Egbe ni fun mi, nitori mo gbé, nitoriti mo jẹ́ ẹni-alaimọ́ etè, …nitoriti oju mi ti ri Ọba, OLUWA awọn ọmọ-ogun.” Riri iwa-Ọlọrun ayeraye ninu pipe ẹwa iwa mimọ́ mu ki o ri ipo ti oun paapaa wà. Eyi mu ki o mọ̀ pe iwa ẹ̀ṣẹ-abinibi ṣi wà sibẹ ninu ọkàn rẹ̀ eyi ti a gbọdọ fà tu kuro. O ri i bi oun ti ṣe alaiyẹ tó. Riri ti o ri ara rẹ̀ ni iru ipo bayii mu ki o ṣeeṣe fun Ọlọrun lati ṣe iṣẹ iwẹnu ninu ọkàn rẹ̀ eyi ti a n pe ni isọdimimọ́ patapata.

O dara fun wa lati ri ara wa gẹgẹ bi Ọlọrun ti ri wa. Bi a ba ṣe bẹẹ, yoo mu ki a ke pe Ọlọrun fun iranwọ́. Nigba naa Ọlọrun le ṣiṣẹ fun wa, ki o si ṣe ohun ti O ba fẹ fun wa. A fi Ọrọ Ọlọrun ṣe awojiji. A gbọdọ maa wo awojiji naa nigbakuugba pẹlu adura ninu ọkàn wa pe ki a le ri i bi awa ti ri gan an nibẹ. Olukuluku ẹni ti kò ti i ri isọdimimọ́ gbà ni lati mu ọkàn le, “nitori eyi ni ifẹ Ọlọrun, ani wiwà ni mimọ́ nyin” (1 Tẹssalonika 4:3). Awa ti a si ti ri iriri ologo nì si tun le yẹ ara wa wò ninu Ọrọ ti n wáni ri nì, nitori a gbọdọ wẹ ara wa mọ́, gẹgẹ bi Oun ti mọ́, ki a si maa ti “igbagbọ́ de igbagbọ́,” ati lati inu ogo de inu ogo, titi awa o fi ri I gẹgẹ bi Oun ti ri, ki a si dabi Rẹ̀ nipa oore-ọfẹ iyanu Rẹ̀.

Ninu agọ ti o wà ni ayé, ọna iyanu ni iná n gbà de ori pẹpẹ idẹ, a si n mu ẹ̀ṣẹ́-iná lati ori pẹpẹ-idẹ si Ibi Mimọ́ a si n fi sori pẹpẹ-wura ti turari, èéfín eyi ti n goke tọsantoru sọdọ Ọlọrun. Eyi jẹ apẹẹrẹ isọdimimọ́ patapata. Ọkan ninu awọn serafu mú ẹ̀ṣẹ́-iná lati ori pẹpẹ o si fi kan ète Isaiah, a si kede rẹ pe, “a mu aiṣedede rẹ kuro, a si fọ ẹ̀ṣẹ rẹ nù.” Nitori naa a le sọ pẹlu idani loju pe a sọ Isaiah di mimọ́.

Isọdimimọ́ Isaiah ki i ṣe ohun ti o ṣẹlẹ diẹdiẹ. Iriri ẹsẹkẹsẹ ni. Oun kò dagba lọ sinu iwa mimọ́, tabi ki o ri i ki a maa mu ẹ̀ṣẹ-abinibi rẹ̀ kuro diẹdiẹ. Ni iṣẹju kan Isaiah ri ara rẹ̀ bi eleeri, ṣugbọn ni iṣẹju ti o tẹle e o gbọ ohùn serafu nì ti o wi fun un pe o ti di mimọ́ laulau. Isọdimimọ́ jẹ́ iṣẹ iwẹnumọ ọkàn ti igbagbọ́ n mu wá lẹyin igba ti ẹni ti n wá iriri yii ti ya ara, ẹmi, ọkàn ati ayé rẹ̀ sọtọ patapata.

A le ṣe akiyesi pe ẹ̀ṣẹ́-iná ti a mú lati ori pẹpẹ jẹ apẹẹrẹ **iná atunniṣe** ti Ẹmi Mimọ́, ki i si ṣe **ti agbára ti a n ri gba** nigba ti a ba fi Ẹmi Mimọ́ wọ ni. Idarudapọ ma n wà nigba ti awọn eniyan ba n ṣe alaye ti kò péye nipa ifi Ẹmi Mimọ́ wọ ni, eyi ti i ṣe iriri kẹta Onigbagbọ́ ti o dáju. A sọ Isaiah di mimọ́-- a mu aiṣedeedee rẹ̀ kuro, a si wẹ ẹdá ẹ̀ṣẹ rẹ̀ nù – nigba ti ẹ̀ṣẹ́-iná naa kan etè rẹ̀. A kò fi iru agbára ti Ẹmi Mimọ́ maa n fi fun awọn ti o ti gba Ileri Baba fun un nigba naa. Iriri Isaiah jẹ́ iṣẹ iwẹnumọ ti Ẹmi Mimọ́ n ṣe. O jẹ ibuwọn Ẹjẹ iwẹnu -- ẹ̀ṣẹ́-iná atunniṣe – ti n pese wa silẹ fun ifiwọni Ẹmi Mimọ́ ni kikun agbàra Rẹ̀. A n fun wa ni agbara yii nigba ti a ba ri iriri kẹta ti Onigbagbọ́ -- fifi Ẹmi Mimọ́ wọ ni.

A sọ Isaiah di mimọ́, ṣugbọn a kò fi Ẹmi Mimọ wọ eniyan ṣiwaju Ọjọ Pẹntikọsti. Olutunu naa kò dé titi di igba ti Jesu fi goke re Ọrun, nitori naa kò si ninu awọn eniyan mimọ́ igba Majẹmu Laelae ti a fi Ẹmi Mimọ́ wọ̀. Ṣugbọn aimoye ninu awọn eniyan mimọ́ ti Majẹmu Laelae ni a sọ di mimọ́, wọn si jẹri si otitọ naa nipa isin wọn lori ilẹ aye yii ninu pipe iwa-mimọ́ yii eyi ti o jẹ kiki awọn ti a sọ di mimọ́ ni o le mọ̀.

**Iṣẹ ti a fi Rán Isaiah**

Olukuluku eniyan ni Ọlọrun pè. Diẹ ni o jẹ́ ipè naa, Ọlọrun si yàn wọn, bi wọn si ti n foriti i lọna iwa-bi-Ọlọrun wọn jẹ oloootọ (Matteu 20:16; Ifihan 17:14). Awọn kan ninu awọn ti o jẹ ipe Ọlọrun si igbala ni a pè, ti a si yàn si awọn iṣẹ pataki ninu isin Rẹ̀ (1 Kọrinti 12:28; Efesu 4:11-13). A ti pe Isaiah ni wolii Ọlọrun paapaa ṣiwaju isọdimimọ́ rẹ̀, ṣugbọn nigba ti a wẹ ẹ mọ kuro ninu ẹ̀ṣẹ-abinibi, ipè rẹ̀ wá yanju kedere, a si fun un ni iṣẹ pataki lati ṣe nipa orilẹ-ède Israẹli apẹyinda.

A fi iṣẹ pataki rán Isaiah si awọn eniyan, ki wọn ma ba tẹra mọ́ ọ̀na iwa buburu wọn ti iyọrisi rẹ jẹ́ okunkun ati ikolẹru. A yàn án fun iṣẹ pataki yii, a si pese rẹ̀ fun un. Gbogbo iwe asọtẹlẹ rẹ̀ jẹri si i pe oun jẹ́ oloootọ si ipè rẹ̀ ati si awọn eniyan rẹ̀. Ohun nla ribiribi ti o yani lẹnu ni a fi hàn wá ninu ọ̀rọ ti o mu wa fun wa lati ọdọ Ọlọrun nipa imisi Ẹmi Mimọ́. Idajọ ti o bani lẹru ati èṣe ti o nira ti n tẹle ẹ̀ṣẹ didá ati iṣọtẹ si Ọlọrun, ni a kọ sinu iwe Isaiah. A pè é, a yàn án, o si jẹ oloootọ ani titi de ikú.

## AWỌN IBEERE

1 Sọ awọn otitọ pataki nipa ti Ọlọrun ti a kọ́ wa ninu iran Isaiah.

2 Bawo ni a ṣe mọ̀ ninu ibi ti a kà fun ẹkọ wa ati ibomiran ninu Iwe Mimọ́ pe Ẹni Mẹta ọtọọtọ ni o wà ninu Iwa-Ọlọrun?

3 Ki ni abayọrisi ifarahàn Ọlọrun lori Tẹmpili funra rẹ̀?

4 Ki ni abayọrisi ìran naa lori Isaiah?

5 Ki ni serafu naa ṣe ati ki ni o si sọ si ọ̀rọ ti Isaiah sọ nipa ti ara rẹ̀?

6 Bawo ni a ṣe mọ̀ pe a sọ Isaiah di mimọ́ ni akoko yii?

7 Bawo ni a ṣe mọ̀ pe a kò fi Ẹmi Mimọ́ wọ Isaiah ni akoko yii?